# OUNJẸ ALẸ IKẸHIN ATI GẸTSEMANE
## Matteu 26:17-46; Johannu 13:1-17; I Kọrinti 11:23-30
## ẸKỌ 62 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Nitori nigbakũgba ti ẹnyin ba njẹ akara yi, ti ẹnyin ba si nmu ago yi, ẹnyin nkede ikú Oluwa titi yio fi de" (I Kọrinti 11:26).**

**I Ajọ Irekọja Ikẹhin**

1 Awọn ọmọ-ẹhin palẹ mọ fun ase naa, Matteu 26:17-19; Marku 14:12-16; Luku 22:7-13
2 Jesu sọ nipa bi a o ti ṣe fi Oun hàn, Matteu 26:20-25; Marku 14:18-21; Luku 22:21-23; Johannu 13:21-30

**II A Da Ounjẹ Alẹ Oluwa Silẹ**

1. A bu akara iye naa, Matteu 26:26; Johannu 6:51; Marku 14:22; Luku 22:19; I Kọrinti 11:24
2. Aago naa duro fun apẹẹrẹ Ẹ̀jẹ ti majẹmu titun, Matteu 26:27-29; Marku 14:23-25; Luku 22:20; Heberu 9:16-23; I Kọrinti 11:25, 26
3. Bi ilana yi ti ni ọwọ̀ to beere yiyẹ ọkan ẹni wò, I Kọrinti 11:27, 28
4. "Ẹnikẹni ti o ba njẹ, ti o ba si nmu laimọ̀ ara Oluwa yatọ o njẹ, o si nmu ẹbi fun ara rẹ," I Kọrinti 11:29, 30

**III Wiwẹ Ẹsẹ Awọn Ọmọ-Ẹhin**

5. "Bi nwọn si ti pari onjẹ alẹ" Jesu bẹrẹ si i wẹ ẹsẹ awọn ọmọ-ẹhin, Johannu 13:1-5
6. "Bi emi kò ba wẹ̀ ọ, iwo kò ni ipin lọdọ mi," Johannu 13:6-11
7. 'Mo ti fi apẽrẹ fun nyin," Johannu 13:12-16
8. "Bi ẹnyin ba mọ̀ nkan wọnyi, alabukun-fun ni nyin, bi ẹnyin ba nṣe wọn," Johannu 13:17

**IV Ninu Ọgba**

9. Jesu gbadura "ifẹ tirẹ ni ki a ṣe," Matteu 26:36-42; Marku 14:32-36; Luku 22:39-42
10. "Ogùn rẹ̀ si dabi iro ẹ̀jẹ nla," Luku 22:44
11. Angẹli kan gba A niyanju, Luku 22:43
12. "Kili ẹnyin nsùn si? ẹ dide, ẹ mã gbadura, ki ẹnyin ki o máṣe bọ́ sinu idẹwò," Luku22:46; Matteu 26:40-46; Marku 14:37-42

## ALAYE

### Ajọ Irekọja Kinni

A dá Ajọ Irekọja silẹ ni Egipti ni orú ọjọ ti a fẹ gba awọn Ọmọ Israẹli là kuro ninu oko-ẹrú. Oluwa fun Mose ni awọn aṣẹ ti o yanju kedere nipa bi won ti ṣe ni lati pa a mọ́ (Ẹksodu 12). Idile kọọkan ni lati mu akọ ọdọ-agutan ti kò labawọn ki o si ya a sọtọ kuro laarin agbo lati ọjọ kẹwa titi di ọjọ kẹrinla oṣu. Gbogbo ijọ eniyan Israẹli ni o ni lati pa ọdọ-agutan naa ni laẹ ọjọ kẹrinla. Wọn si ni lati fi ẹjẹ naa wọ́n ẹgbẹ mejeeji ati àtẹrigba ilẹkun. Ẹ̀jẹ yi jẹ àmi fun angẹli apanirun lati dá awọn ti o wà ninu iru agbo ile bẹẹ si kuro ninu iparun ti a rán si Egipti. O kere tan ọdọ-agutan kọọkan ti a pa ni alẹ ọjọ naa gba ẹmi eniyan kọọkan là. Melomelo ni ọpọlọpọ ẹmi ti a ti ti ipasẹ Kristi Ọdọ-Agutan Irekọja wa gbala! (I Kọrinti 5:7).

Apẹẹrẹ kristi yi peye to bẹẹ gẹẹ, igbala naa si jẹ iyalẹnu to bẹẹ ti Oluwa fi paṣẹ pe ki ọjọ yi ki o jẹ ọjọ irnati titi laelae (Ẹksodu 12:14). "Oṣu ti a ikiyesi ni gidigidi si OLUWA ni mimú wọn jade kuro ni ilẹ Egipti: eyi li oru ti a ikiyesi si OLUWA, li ati irandiran gbogbo awọn ọmọ Israẹli" (Ẹksodu 12:42).

### Ẹbọ Pipe

Ni ọjọ kẹwa oṣu, Jesu rin irin-ajo Rẹ̀ ikẹhin lọ si Jerusalẹmu. Ni ọjọ kẹrinla oṣu, Jesu pa Ajọ Irekọja mọ pẹlu awọn ọmọ-ẹhin Rẹ̀. Nipa ikú Rẹ̀, Jesu mu Irekọja ṣẹ fun wa. Gẹgẹ bi Onigbagbọ́, awa ki i ṣe ajọdun ọjọ ti a gba awọn Ọmọ Israẹli là kuro ni Egipti, nitori a ti ṣe igbala ti o tobi ju bẹẹ lọ silẹ. Jesu fun wa ni ilana Ounjẹ Alẹ Oluwa ki olukuluku Onigbagbọ́ ba le maa ranti igbal nla ti Jesu fi ikú Rẹ̀ rà fun wa ki a ba le wa laaye.

Nigba pupọ ni Jesu ba awọn ẹlẹṣẹ jẹun, ṣugbọn ni alẹ ọwọ̀ yi, O pejọ pọ pẹlu awọn ọmọ-ẹhin Rẹ̀. Ọkan ninu awọn Ofin Ajọ Irekọja ni pe alejokalejo kò gbọdọ jẹ ninu rẹ (Ẹksodu 12:43).

### Awọn ti o Yẹ lati Jẹ ẹ

Awọn ti a tunbi lotitọ ti won si n gbe igbesi-aye Onigbagbọ́ nikan ni o ni ẹtọ lati jẹ Ounjẹ Alẹ Oluwa. "Ki enia ki o wadi ara rẹ daju, bẽni ki o si jẹ inu akara na ki o si mu ninu ago na. Nitori ẹnikẹni ti o ba njẹ ti o ba si nmu laimọ̀ ara Oluwa yatọ, o njẹ, o si nmu ẹbi fun ara rẹ̀" (I Kọrinti 11:28, 29).

Awọn miran wà ti ọrọ wọnyi ṣajeji si nipa jijẹ́ alai yẹ lati jẹ Ounjẹ Alẹ Oluwa. Kedere ni ọrọ naa. Paulu ti n bá wọn wi nitori aiṣe nkan tọwọtọwọ ninu Ile Oluwa, ati nitori iyapa ti o wà laarin wọn. O n rán wọn leti ironu ti o wa ninu pipa ilana ti a dá silẹ ni iranti ikú Kristi lori agbelebu mọ́, ati ni wiwọ̀na fun bibọ̀ Rẹ̀. Bi a ba ti ni igbala ti a ba si n rin ninu imọlẹ pẹlu ipinnu ninu wa lati tẹle Oluwa, nigba naa a kò ni jẹ bẹẹ ni a ko si ni mu ohun wọnni ti wọn jẹ apẹẹrẹ Ounjẹ Alẹ Oluwa lai yẹ.

Ọlọrun n fẹ ki a wá siwaju Oun tọ̀wọ̀tọ̀tọ̀, ki o si ye wa pe a n jẹ ẹ ni iranti ikú Oluwa. Ninu gbogbo akoko iṣẹ-iranṣẹ Jesu Kristi, lai ṣe aniani, akoko ti o ni ironu ju lọ ni eyi ti O lo ni oru nì ni Ọgba Gẹtsemane nigba ti O fi irora gbadura pe, "Bi o ba le ṣe, jẹ ki ago yi ki o kọja kuro lori mi." Aago ijiya nì, aago ikú ni. Nitori naa nigba ti a ba pejọ si tabili Oluwa lati ṣe alabapin ninu waini ati akara, ti i ṣe apẹẹrẹ ara ati ẹ̀jẹ Jesu, èro wa ni lati wà lara Rẹ̀ ki a si fa ọkan wa soke ọrun pẹlu adura ifar-rubọ ati yiya aye wa sọtọ fun Un lọtun.

**Apẹẹrẹ Ara ati Ẹ̀jẹ Kristi**

Awa kò gbagbọ́ pe ara ati ẹ̀jẹ Jesu gan an ni a n jẹ ti a si n mu nigba ti a ba n jẹ ounjẹAlẹ-Oluwa. Nigba ti a ba gbadura sori ohun wọnni ti a gbe kalẹ, wọn ki i pada di ẹ̀jẹ ati ara Jesu gẹgẹ bi awọn kan ti rò. Ṣugbọn wọn niye lori fun wa gẹgẹ bi apẹẹrẹ iru eyi ti Jesu gbadura le lori ni alẹ Ase-alẹ ikẹhin. Bi a ba mọ ara Oluwa yatọ a le wo Ọlọrun fun agbara iwosan ti o wà ninu Ẹ̀jẹ naa. Bi a ba n ṣaisan ninu ara, bi a ba ni irora kan, bi idanwo ba wọ wa lọrun, ẹ jẹ ki a mọ ara Ọlọrun yatọ -- ki a mọ̀ pe O kú ki awa ba le yè -- a o si ri agbara Ọlọrun gbà fun ohun ti a n fẹ.

O lodi si Ọrọ Ọlọrun lati lo omi dipo waini. Omi eso ajara ti ko I bà ni a ni lati lò. Kristi ati awọn ọmọ-ẹhin Rẹ̀ lo "eso ajara" (Matteu 26:29; Marku 14;25; Luku 22:18). Ko si ibi kan ninu Ọrọ Ọlọrun ti a le ri i pe Jesu lo omi nigba ti O dá Ounjẹ-alẹ Oluwa silẹ. Ọlọrun n fẹ ki a tẹle Ọrọ naa.

**Ilana ti Ẹsẹ Wiwẹ**

Lẹhin ti O ti dá Ounjẹ-alẹ Oluwa silẹ, Jesu fi agbada Rẹ̀ lelẹ si apa kan, O mu gele O si di ara Rẹ̀ ni amure. Lẹhin naa O bu omi sinu awokoto kan, O si bẹrẹ si i maa wẹ̀ ẹsẹ awọn ọmọ ẹhin. Ọrọ Jesu fi hàn gbangba pe wiwẹ ẹsẹ awọn ọmọ-ẹhin jẹ kókó kan ninu awọn ilana Onigbagbọ́. Peteru wi fun Kristi pe, "Iwọ ki yio wẹ̀ mi li ẹsẹ lai" (Johannu 13:8). Idahun Kristi ti to: "Bi emi kò ba wẹ̀ ọ, iwọ ko ni ipin lọdọ mi." Lẹhin ti Jesu wẹ̀ ẹsẹ awọn ọmọ-ẹhin tan ti O si joko, O wi pe, "Ẹnyin mọ̀ ohun ti mo ṣe si nyin?" Nigba naa ni O fun wọn ni itọni nipa pipa ilana yi mọ́.

Jesu wi pe, "Bi emi ti i ṣe Oluwa ati Olukọni nyin ba wẹ̀ ẹsẹ nyin, o tọ́ ki ẹnyin pẹlu si mã wẹ̀ ẹsẹ ara nyin. Nitori mo ti fi apẹ̃rẹ fun nyin, ki ẹnyin ki o le mã ṣe gẹgẹ bi mo ti ṣe si nyin." Ọpọlọpọ awawi ni awọn ti n ṣaigbọran si ọrọ yi n ṣe; ọkan ninu awọn awawi naa ti o papọju ni pe o jẹ aṣa ni ọjọ wọnni lati maa wẹ̀ ẹsẹ wọn ki wọn to wọle, nitori pe salubata ni won n wọ̀. Ṣugbọn wọn ni lati ti ṣe eyi tẹlẹ, nitori pe wọn ti wọle wọn si ti jẹun tan.

Ẹsẹ wiwẹ jù aṣ lọ. Apẹẹrẹ kan ni Jesu fi lelẹ; ilana kan ni O n fi fun wọn ti awọn ọmọ-ẹhin olufọkansin tootọ ni lati maa pamọ́ lati ọdun de ọdun. Ọkan ninu iyin ti Paulu fi fun awọn eniyan mimọ́ ni pe wọn ti "wẹ ẹsẹ awọn enia-mimọ́." Anfaani ni o jẹ fun wa lati gbọran si awọn ilana Jesu. O ti ṣeleri ibukun fun wa fun igbọran. "Bi ẹnyin ba mọ̀ nkan wọnyi, alabukun-fun ni nyin, bi ẹnyin ba nṣe won" (Johannu 13:17). Eniyan pupọ ni o n padanu ibukun ti Jesu ti ṣeleri, nipa kikuna lati pa ilana ẹsẹ wiwẹ mọ́.

**Oun Nikan Ninu Adura**

Bi o tilẹ jẹ pe alẹ yi ni anfaani ikẹhin ti Jesu ni ṣiwaju ikú Rẹ̀ lati wà pẹlu awọn ọmọ-ẹhin Rẹ̀, O wá akoko lati dá nikan lọ gbadura. O rọrun lati jẹ ki iṣẹ pupọ dù a ni akoko adura; ṣugbọn adura lo n fun ni lokun lati bori idanwo ati lati ṣe nkan fun Ọlọrun. Ẹnu ya Jesu si ailera Peteru O si kigbe wipe "Kinla, ẹnyin ko le ba mi ṣọ́na ni wakati kan?" "Ẹ mã ṣọ́na, ki ẹ si mã gbadura, ki ẹnyin ki o má ba bọ sinu idẹwò." Peteru sun lọ nigba ti i ba ti ṣọna. Nitori bẹẹ nigba ti idanwo de, kò ni agbara. O kuna o si sẹ́ Oluwa rẹ. Jesu tẹ siwaju ninu adura iwaya-ija. A ka pe "Angẹli kan si yọ si i lati ọrun wá, ó n gbà a ni iyanju. Bi O si ti wa ni iwaya-ija O n gbadura si i kikankikan: õgùn rẹ̀ si dabi iro ẹjẹ nla, o nkan silẹ" (Luku 22:43, 44). Nipa iṣẹgun ti O ri gbà ni Gẹtsemane ni O fi le ṣe iṣẹ igbala yọri lori Agbelebu Kalfari.

**AWỌN IBEERE**

1. Kin ni ileri ti a ṣe fun igbọran si ilana ẹsẹ wiwẹ̀?
2. Kin ni awawi ti awọn ẹlomiran maa n wi fun ṣiṣaigbọran si ilana yi, bawo ni iwọ si ti ṣe le dahun si i?
3. Iwọ ha gbagbọ pe akara ati waini naa n pada di ara ati ẹjẹ Kristi gan an nigba ti a ba gbadura le wọn lori?
4. Kin ni itumọ pe eniyan n jẹ o si n mu Ounjẹ Alẹ Oluwa lai yẹ?
5. Ẹlẹṣẹ ha le ni ipin ninu Ounjẹ Alẹ Oluwa?
6. Nigba wo ni Ajọ Irekọja kinni?
7. Kin ni akara ati waini duro fun ninu Ounjẹ Alẹ Oluwa?
8. Eeṣe ti Peteru fi yi ero rẹ pada nipa jijẹ ki Jesu wẹ ẹsẹ rẹ?
9. Eeṣe ti a fi n jẹ Ounjẹ Alẹ Oluwa?
10. O ti pẹ to lẹhin pipa ilana Ounjẹ-alẹ Oluwa mọ́ ki Judasi to fi Jesu hàn?
11. Kin ni anfaani adura ti Jesu gbà ninu Ọgba nì?
12. Kin ni Peteru, Jakọbu ati Johannu n ṣe lakoko ti Jesu n gbadura ninu Ọgba naa?